# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JẸ ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. III. No. 120. SATURDAY, NOV 1, 1924. FOURPENCE.

**DURO THOMAS.**

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods,*

**"Specialities: Enamelware Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads etc., etc., etc."**

---

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

OYINBO ***J. F. SICK***

Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirişi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Waji, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Òlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọny fun tita :—

Ikoko taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn onjẹ Ipanu, aşọ iş'ọşọ, Ẹrọ ere ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹla (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Maşini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile owo ni :— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD.

## No. 1, LAGOS.

LEVER STORES LIMITED

# OLOWO S'OKE D'ILẸ

A ni oriṣiriṣi ọja fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

A nta awọn ọja wa ni :—

**3d. 6d. 9d. 1s.**

A nṣi ilẹkun di agogo kan ọsọsan Thursday.

A si nti ilẹkun ni agogo meje alalẹ Satide.

*Editor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Offices : 22 & 24*, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### AJẸ NKE OKUNRUN KO PARADA, O LOWO ẸBỌ NI'LE ?

Ki afara maṣe já gbogbo awọn ti a ti fi iwe pe lati wa jọsin f'Ọba ati ilu wọn, nipa Ṣiṣe iṣẹ *Jury* lati ọtunla nigbati a o ṣi Kotu Ganran fun ẹjọ oṣu mẹtamẹta na ; a gbọ pe awọn ẹjọ pataki diẹ nbẹ ninu wọn ni riro bi ẹjọ ti Epo Oyinbo ! Epo Antie ! ! Epo Burọda ! ! !

### ỌBA MẸWA, IGBA MẸWA.
### (*SERIKI GOMA, SỌMỌNU GOMA.*)

O jẹ ohun ti o ṣi wa lori gidigidi lati gbọ pe awọn Ijoye Onifila funfun wa lọ sọdọ Oyinbo Ọgbẹni Ọgagun W. Birrel Grey, Balẹ Ilu nisinsinyi fun Ipade kan lẹnu ọsẹ to kọja ; a si tun gbọ pe t'ọwọ-t'ẹsẹ ni Balẹ na fi gba nwọn, ti o si sọ fun wọn pe inu on yio dun ti awọn Ijoye wa na ba gbọjẹgẹ ki on ma ba wọn ni Ipade lẹkọkan loṣoṣu fun ilọsiwaju iṣẹ, rere, ati anfani ilu ; a si sọ pe obi gbó s'ẹnu Oloye Oluwa fun esi jijọlọ ti o fun Balẹ wa na.

Bẹ̄bẹ̄ ni k'a ma ri o !

### LỌYA JIGA RE IBADAN NI'LE OLUYỌLE.

Ọgbẹni J. Egerton Shyngle Ọlọla dakan lọ si Ibadan fun ẹjọ *Assize* kan yio si pada bọ wa'le ni ọsẹ yi. Abọ o !

### ỌMỌ KEKERE ẸJẸ ỌRUN.

Igbe "yê yê" ti a gbọ ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi niwọn aṣalẹ ni eti ile Ọgbẹni Alagba Sunmọnu Oridẹdi Ladẹyọ ni *Victoria Street*, mu'wa ati ọrẹ wa kan ti t'awa tirẹ njọ nlọ sode takiji nigbati a ri ọmọ jojolo kan ti ko ju ọmọ ọdun mẹrin pere lọ ti "Mọto" L147 gũn u gărũgã lori—ibẹ ko gb'ẹsẹ. A-wa Mọto pẹlu Ọlọpa ode ati Panapana f'ori le ti Dr. Macaulay to wa nitosi ibẹ, ṣugbọn ko si ni'le ; nikẹhin ni nwọn wa gbe ọmọ na lọ si ti Dokita Vaughan fun itọju ; a bẹ awọn Obi ati Alagbato ọmọ ki nwọn maṣe ma jẹ ki awọn ọmọ pinnişin da nikan rin loju ọna Mọto papa loju "Agan" bi Ẹhin-ọgba tabi ikorita Ita Tinubu, ki Eṣu ma lọ ṣe Charlie o !

### ILU, Ẹ JIGIRI, Ẹ F'AYO NYIN HAN ; KINIUN ONIBUDO NLO S'ỌMỌ ỌGỌTA ODUN ; Ẹ FI IYIN FUN BABA OGO Ẹ FI IYIN FUN BABA OGO.

A ri Iwe gàdàgbàgàdàgbà kan kà ni *Wednesday* ọsẹ yi nipa ti ipalẹmọ ti a nṣe fun ajọyọ iranti ọjọ ibi Ọgbẹni wa Herbert Macaulay C.E. (ẹniti yio di ọmọ ọgọta ọdun ni ọjọ kẹrinla oṣu to nbọ lagbara Sòkó ) ti ilu npete lati ṣe, bẹrẹ lati ọjọ kẹrinla oṣu to mbọ ( ti o jẹ ayajọ ọjọ ti a f'ori Kiniun Onibudo sọ'lẹ nigboro Eko pãpã. ) Ipalẹmọ na nfẹ owo ọpọlọpọ lati fi ṣe ẹyẹ ti o yẹ gbogbo ohun ti a o ṣe na, a si tanma pe ẹnyin ara wa ni igbárá ni igboro, ni'le l'ajo ati l'oko yio jẹwọ ọmọluwabi lati ni ọwọ ninu nkan ribiribi yi nipa fifi owo ṣe iranwọ fun yiyanju gbogbo ariya na ; a tẹ̀ bi a o ti wé èwé ọna ti ariya na yio gba sinu iwe *Eko Akete* t'oni.

A ke si nyin o, gbogbo ilu, ẹ jẹ ka fi ohun kan ṣọpẹ lọwọ Ọbangiji Ọba Ogo, fun ọrẹ nlá-nlã ti o fi Ọgbẹni wa na ta wa, ki a si ba baba wa yi yọ ayọ atọkan wa fun oju rere ti o ri gba lọdọ Olodumare, lati iwọn ọgọta ọdun wa, titi di isinsinyi.

Ki Oluwa m'ọjọ ro, Aṣẹ.

### KINI EMI NYIN?

Bi ọkọnrin ara-oke kan ti din'rẹsi (*dress*) to si ṣe gágá ti o wọ inu ọkọ-ero Reluwe lati lọ si ilu rẹ, ni *Thursday* ọsẹ yi nigbati ọkọ Kano fẹ lọ, ni Ido, bẹni o ṣubu korobata sinu ọkọ. Kiloṣe? Kiloṣe? Kiloṣe? Eyi ti a nwi yi ti pẹ, bẹni ọkọnrin na di oku bi idan! Bi iṣẹju, awọn "Akẹran" ti gbe e, rẹrẹ, o di ile-oku-lila, nṣe ni awọn ero toku ni ibi ti ọkọnrin na joko si, yara npalẹ ẹru wọn mọ, o di b'o lọ, o ya ni. ṣugbọn ọwọ awọn "Ara'bi" tẹ wọn, o di Ikoyi nun!!! Ki Baba fi ṣisọ rẹ sọ wa: Igi da! Iji ja!!!

---

Anu ṣe ni pupọ lati gbọ iku Mrs. Jemima Newton, ẹniti ọkọ rẹ nṣe *District Superintendent*, ni k u t u k u t u ãrọ *Wednesday* Alaruba, ọsẹ yi, ni Ebute Mẹta. Obinrin yi jẹ oninu rere, o si ni ọyaya pupọ. Ki Oluwa Ọba Ogo ko gbe si afẹfẹ rere, ki O si t'ọju awọn ọmọ rẹ, a ki gbogbo ẹbi rẹ ku ọfọ ajalu yi.

---

O jẹ iyanlẹnu lati gbọ iku ọdọmọdekunrin, ọmọ Salamọtu Oki, ti a npe ni Tijani to ṣẹlẹ ni Ile Alarun, ni Ikoyi, ni ọsẹ to kọja. Ki Oluwa ki o tu awọn ẹbi ọmọde yi ninu, ki O si parọ ọmọ miran fun iya rẹ.

---

## IROHIN NIPA APEJỌ CBOGBOGBO TI ILU

ti Ọgbẹni Adeoye Deniga pe si ile Afari-Ogun ni ijọ *Thursday* (Alamisi) ijọ kẹtalelogun oṣu to kọja nipa riro ọna ti a fi ma ṣe ẹyẹ ati ohun iwuri fun Ọgbẹni Herbert Macaulay, C.E., ẹniti yio di ọmọ ọgọta ọdun ni ọjọ kẹrinla oṣu yi.

---

Ipade yi ṣi ni agogo marun kọja diẹ. Ọgbẹni Adeoye Deniga da ni imọran si gbogbo ẹgbẹ wipe ki Ọgbẹni A. Ade. Oshodi ṣe alakoso wa ninu Ipade yi, gbogbo ẹgbe si gba imọran na, Ọgbẹni Ade. Oshodi si bọ si ori aga. Ki a to bẹrẹ si ọrọ sisọ ni Ọgbẹni Deniga si pe Ọgbẹni John A. Tade. Bright ki o ba wa ṣe Akọwe-ẹgbẹ nipa kikọ ọrọ ti ẹgbẹ ba sọ silẹ o si gba (ko si ẹniti ko mọ Ọgbẹni Tade. Bright nipa iru iṣẹ bẹ.)

Alaga ẹgbẹ yi si pe Ọgbẹni to pe ipade yi ko sọ idi ohun to ṣe pe irufẹ ipade bẹ, Ọgbẹni Deniga dide o t'ẹnu bọ akó ọrọ wipe o tọ o si yẹ ki a ṣe ohun iwuri to yẹ fun Ọgbẹni Herbert Macaulay, C.E., fun ọgọta ọdun to ma da ni oṣu yi nitori ore to ṣe fun ilẹ yi lati ọdun jọjọ sẹhin, papa niti ọrọ ilẹ li arin awa Enia Dudu to mbẹ mba ihin to si jẹ pe ninu ti ilu, lẹhin ilu lo wa, ire ilu lo nlẹ, irufẹ ẹni bẹ o tọ ki a ṣe ohun iwuri fun, o si mu aworan Macaulay s'ode eyiti nwọn nta ni lọlọyi titi di oni, o si sọ gẹgẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ fun wa gẹgẹ bi Enia Dudu wipe ka ni aworan Ọgbẹni yi ni ile fun awọn iran to mbọ l'ẹhin, ki nwọn le ma ri aworan ẹni wa yi.

Alaga si sọ wipe o tọ ati wipe o si yẹ ki a ṣe ohun ribiribi fun Ọgbẹni wa yi, asiko to si tọ fun wa lati ṣe ni ayajọ ti a bi nitorina ki Ọgbẹni Deniga fi eto gẹgẹ bi a o ti ṣe han wa, eyiti o kọ silẹ ninu iwe kan.

Ọgbẹni Deniga si ka awọn eto wọnyi :—

Ekini :—Ni ijọ kẹrinla oṣu *November* ti Ọgbẹni wa Herbert Macaulay C.E. ma di ọmọ ọgọta ọdun, ipade gbogbogbo yio wa ni ile Afari-Ogun (*Glover Memorial Hall*) ni agogo mẹjọ abọ alẹ eyiti Ọgbẹni Dokita Moses Da Rocha olohun iyọ ma ba gbogbo ilu sọrọ nipa Herbert Macaulay, nibiti ẹgbẹ ma gbọ rafanda ọrọ, lẹhinna awowo yio wa nibẹ lalẹ ọjọ na.

Ekeji :—Onjẹ ati nkan mimu yio wa ni'le alase ti Ọgbẹni Rahm ibiti a npe ni *Bonanza Hotel* ni ijọ kẹtadinlogun oṣu l'ọjọ *Monday* lati agogo mẹjọ alẹ.

Ẹkẹta :—Ni ogunjọ oṣu (*Thursday*) ijọ Alamisi l'agogo mẹjọ abọ alẹ orişirişi ijo ilẹ wa yio wa ni ile Afari-Ogun (*Glover Memorial Hall.*)

Ẹkẹrin :—Pari-pari rẹ niyi, ni ijọ Satide ijọ kejilelogun oṣu ni ọgba ile Afari-Ogun (*Glover Memorial Hall*) a o gba aworan eyiti Ọgbẹni Herbert Macaulay C.E. yio wa ni arin wa.

Alaga si sọ wipe o yẹ wipe ka fun Ọgbẹni Herbert Macaulay C.E. ni *apo* (*purse*) fun ọgọta ọdun rẹ.

(1) Ọgbẹni Oluyẹle Bright yombo aba ati imọran ohun aṣeyẹ yi fun Ọgbẹni Herbert Macaulay, o si wipe on ro pe o yẹ ki ẹgbẹ (Tunluṣe) *The Nigerian National Democratic Party* ati ẹgbẹ miran lọwọ ninu rẹ, nitori ko si ẹniti ọrọ Ilẹ (*Land Question*) lori eyiti Mọkọli nṣe wahala pupọ si, ko kan.

Ọgbẹni Disu Laniyan wipe ki Alaga jọ ko sọ fun Ọgbẹni Deniga ko tun eto yi ka ki awọn [illegible]lagba to ṣẹṣẹ de ki nwọn le gbọ. Ọgbẹni Deniga ṣe bẹ gẹgẹ bi aṣẹ Alaga.

Ọgbẹni Bankẹfa Ojọmu si da ni imoran wipe o tọ o si yẹ wipe ka ranṣẹ si gbogbo Ile-isin ati Mọṣala ki nwọn ba wa gbadura si ohun ti a fẹ ṣe yi, ati pe ki a le ṣe irufẹ bẹ fun elomiran ti o ba tọ si.

Ọlọla Ata-Amọnu ọmọ-Ọba dide o t'ẹnu bọ ọrọ li ede Oyinbo, wipe Ọgbẹni Herbert Macaulay ti jẹ okunrin to nja fun ilu rẹ lai b'oju wo ẹhin, o ni Ọgbẹni ta ngbero ati ṣe ohun ribiribi fun yi, o tọ fun pupoju o si yẹ bẹ ki a mura lati ṣe ohun to tọ fun, o sọ wipe awọn ẹlomiran le wipe Ọgbẹni Herbert Macaulay jẹ enia rere, ọpọlọpọ si le wipe enia buburu ni, ṣugbọn bi iṣẹ rere ti pọ to, lo mu wa lati pe sibi loni ka lẹ fi ṣe ohun to, tọ fun nitoripe Jesu papa nigbati o wa l'aiye nwọn gan a, nwon ṣanta rẹ lori ọna rẹ kọ ni a ntọ? Bẹna ni Onişẹnla Mọmọdu (Salala) ẹniti o ba ṣe ore, pupọ enia lo ma mọ, pupọ enia lo ma bu nitorina on lọwọ ninu ohun ẹyẹ ti a fẹ ṣe yi.

Ọgbẹni Deniga sọ fun ọpọlọpọ awọn ti ko mọ Ọlọla Ata-Amọnu nigbati o tumọ oro si Yōba, wipe iṣẹ Loya ni o nṣe, on ni Aṣoju Calabar ni Igbimọ Aṣofin (*Legislative Council*) l'Eko ati pe ọmọ-Ọba Anamaboo lo nṣe; aṣa ti ilẹ wọn lo ṣe wa nipa ka da aṣọ bora ka si fi ọja gba ori.

Ọgbẹni Kasunmun Ayọrinde si sọro; ohun pataki to sọ ni pe ni apejọ yi a ri ọpọlọpọ oju titun nibi ati pe obinrin si wa larin wa, a ni lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fun iyẹn, ka le ma jẹ ọrẹ ara wa, nitorina ti a ba fi imọ awọn ẹgbẹ Tunluṣe (*Democratic Party*) si, a dara pupọ.

Ọgbẹni Arinọla Ọkọya da ni imọran pe ko si ọna ti a ma mu ọrọ yi gba ju pe ka tọwọ bọ apo ka fa owo jade lọ, ki olukuluku da owo tirẹ nitori laisi owo nkankan ko le ṣe.

Ọgbẹni Dokita Oguntọla Ṣapara dide lati sọ ọrọ gẹgẹ bi Alaga ti pe ki o da si ọrọ na, bi Dokita ti dide beni gbogbo enia pa atẹwọ gẹgẹ bi inu wọn ti dun lati gbọ ọrọ rẹ, Dokita ki gbogbo enia, o ni loni a ko wa si ibi yi lati wa sọ buruku tabi rere Herbert Macaulay, ṣugbọn a wa si ibi lati wa ro ọna ti a le fi imore wa han fun gbogbo wahala ti Herbert Macaulay nṣe ni Ilu, papa nidi ọrọ ilẹ ti o jẹ ohun iyebiye fun wa, nitori awọn iran to mbọ lẹhin ki nwọn mọ pe Ọgbẹni na ti ja fun ilu, o si sọ pe ẹniti o fi iṣẹ rẹ, ọmọ rẹ, ile rẹ silẹ lọ si ilu Oyinbo lati ja fun ire ilẹ ilu wa, o yẹ fun wa lati ṣe ohun ribiribi fun; o si bere pe talo le fi ile rẹ silẹ fun iru nkan bayi? O ni on papa ko le ṣe bẹ. (Gbogbo enia pa tẹwọ pupọ fun), bawo ni a ti ma ṣe ti ko ni mu idojuti wa, bi a ko ba le ṣe ohun ti o jọju fun u; o tọ o si yẹ ka ṣe ki gbogbo ilu ni ilẹ wa ati Oke Okun (*West Coast*) mọ wipe a ṣe ohun to tọ fun irufẹ ẹni bẹ, ka lẹ fi han wipe a mọ riri iṣẹ rẹ fun wa; lọna bẹ, ka tọwọ bọ apo ka fa nkan jade, atẹwọ bori atẹwọ fun ọrọ Dokita yi tobẹ ti Iya afin Samọta Ikẹ Ọlọrun fi dide to di oṣuṣu fun gẹgẹ bi aṣa ilẹ wa. Lẹhinna ni Dokita Ṣapara wipe on ko ni irufẹ Herbert Macaulay ko si ni gbogbo aiye, on ko wipe ko si enia bi rẹ. Macaulay le buru ni ọna tirẹ bi ẹlomiran ti nwi, ṣugbọn a ko wa sibi lati wa so ohun buburu bikoṣe ore nla pataki to ṣe fun Ilu papa, nigbati ọrọ ilẹ ba de 'lẹ. Ni Ilu Oyinbo aworan ati ere ẹni nla oriṣiriṣi lo wa, ti a nfi han awọn ọmọde, ki awọn na ba ni itara lati le de ipo giga bẹ lẹhin ọla. Ẹnikeni to ba fẹ ki Ilu mọ on, ni lati ṣe ohun ribiribi fun Ilu na. Bi otọ ọro ba de, ki irọ sa lọ, ohun ti Makọli ṣe papa nipa ẹjọ ilẹ to ṣe ni Ilu Oyinbo kun mi loju pupọ—ore nla lo jẹ fun Ilu. Makọli kọ ni a fẹ ṣe ẹyẹ fun, bikoṣe pe a fẹ ti ipasẹ Makọli fi apẹrẹ ẹmi imore silẹ fun awọn ọmọ wa ati iran to mbọ lẹhin.

Alaga ni gẹgẹ bi gbogbo wa ti gba wipe ka fi imọ ẹgbẹ Tunluṣe (*Democratic Party*) ati ẹgbẹ miran si, nipa wipe ki nwọn le ni ọwọ si, gbogbo Ajọ gba, Ajọ si tuka niwọn agogo mẹfa kọja diẹ, awọn ẹniti o wa si Igbimọ to iwọn ogọfa enia, diẹ ti a da orukọ wọn ni wọnyi:—Alaga A. Ade Oshodi, ẹniti o pe apejọ Adeoye Deniga, Ọlọla J. Egerton Shyngle, J. Bagan Benjamin C.E., Ọmọ Ọba Ọlọla K. Ata-Amonu ti Aṣoju awọn Calabar ni Igbimọ Aṣofin, Dokita Oguntola Ṣapara I.S.O., Adeoye Kayode L.L.B., Ayọ Williams B.L., D. A Leigh, D. Ayọdele Bright, H. A. Phillips, Bamkẹta Ọjọmu, J. A. Fakolujọ, Arinọla Ọkọya, Alufa Arinọla Ibaru, Alfred B. Williams, S. A. Johnson, R. A. Staveley, E. A. Ogunmoyero, G. D. Francis, Oluyẹle Bright, T. F. Olukọtun, George I. Phillips, N. A. Ṣolade, I. B. Thomas, E. M. Awobiyi, Kasumu Gbalaja (Bashorun) Jinadu Matti, Kasumu Ayọrinde, Mumuney Animashawun, Disu Laniyan, Samota Ikẹ Ọlọrun, Kaliatu Kẹhinde Lika Ọloja Obinrin, akọwe Ipade John Tade Bright ati ọpọlọpọ ijinmi-ijinmi enia miran.

---

## NIGERIA AND THE NATIONAL CONGRESS.

The National Congress has decided to send delegates from the Gold Coast and Sierra Leone branches to Nigeria in December to attempt to resuscitate local interest in the Congress movement. Nigeria understands the ideals of the movement, but her educated men appear to find the "applied" science of government more interesting than the "pure" variety, and prefer to recognise that the term "African racial aspirations" is a portmanteau phrase, including a range of ideals extending from representative

self-government on the one hand to simple desire to be freed from European domination to carry out more primitive customs on the other. When Nigeria has attained to a more homogeneous structure, and the opinion of a conference at Lagos may with safety be regarded as the opinion of even a quarter of the 18 million inhabitants of the Colony and Protectorate, it will be time for her to consider interesting herself in ideals which the experience of Lagos has proved are not yet practicable.

*West Africa 11/10/24.*

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, NOV. 1, 1924.

## BI DADA KO LE JA, O L'ABURO TO GBOJU.

Ọrọ ti *Congress* ko le ṣe ki o ma jẹ ọran ẹdun fun wa gẹgẹ bi o ti jẹ pe ni gbogbo ilu ti ẹka Ẹgbẹ yi wa lati igbati a ti da silẹ ni idunrin, Eko nikan lo rẹhin bi ògúnná fun ilọsiwaju Ẹgbẹ ribiribi na; bayi kọ lo ri ni ilu Wúrà (*Gold Coast*) pāpā ni *Accra* nibiti a gbe fi ori Ẹgbẹ na sọlẹ si, ni oṣu *March* l'ọdun 1920; bayi kọ lo ri ni ilu Saro, bayi kọ lo ri ni ilu *Gambe* gidipā bayi si kọ lo ri lọdọ awọn Ọmọ Ẹka Ẹgbẹ t'Eko yi ti nwọn wa l'Ebute Mẹta: a wi kukuru a wi gbọ̄rọ, ṣugbọn ko si iyipada kan ti a ri lara ẹka Ẹgbẹ ti ilẹ yi ti o le mu wa f'ọwọ s'ọya pe Ọrọ ko ni pá le Ẹka yi lori ninu oṣu to mbọ, eyiti a nreti awọn Saraki Ẹgbẹ na lati Saro ati ilẹ Wúrà; titi di isinsinyi, a ko gbọ pe ẹka Ẹgbẹ ti Eko nmura lati ṣe fitafita kan nipa mimura silẹ de awọn Ọlọla ti a sọ pe nwọn nbọ lati wa bẹ nwọn wò; bayi ni ẹnyin agbàgbà ẹka Ẹgbẹ yi yio dakẹ? Bayi ni ẹ o la oju nyin silẹ ki Talubọ 'yekan Afọju ko wọ? Bayi ni ẹ o dabi Abata ti o takete bi ẹnipe ko b'odo tan? Bayi ni ẹ o joye Ọlọmu da ọmu iya rẹ gbe? Bayi ni ẹ o fi ọwọ nyin ṣiṣẹ tan lati iye ọdunmọdun yi wa, fun gbigbcrẹgẹjigẹ ẹka Ẹgbẹ na larin wa nibi, ni iwọn ọdun kẹrin ọhun, ti ipade npe ipade ranṣẹ, ni Ilupesi, ti ẹ o si tun fi ẹsẹ ara nyin ti i danu?

A bere gbogbo ibere yi, nitoripe a fẹ ki ẹnyin Àgba-àgbà ti ẹ jẹ Aṣaju ati Olori ẹka Ẹgbẹ *Congress* na ni ilẹ yi, mọ daju-daju pe bi ẹ ko ba jigiri lati wa ọkan ṣe fun ati palẹ awọn Alejo to nbọ yi mọ, ati fun ati mu Ẹka Ẹgbẹ sọji, ki o ma ba iṣẹ rẹ lọ, a woye pe bi ẹnyin tilẹ dakẹ "Okuta yio f'ọhun:" ti o ba si jẹ yọbọkẹ ni ẹ o fi ọran yi ṣe, ti Aburo lẹhin nyin, eyini ni Ẹgbẹ "Demo" (*Nigerian National Democratic Party*) ti o ṣẹṣẹ le ni ọmọ ọdun kan ni koipẹ yi, ba jẹ oye ọmọ kẹhin o gb'ẹgbọn lọwọ nyin nipa imura wọn lati gba awọn Alejo nla ti a nreti yi ni ọsẹ diẹ si tọwọ-tẹsẹ ki oju maṣe ti Eko, ẹnyin ẹka Ẹgbẹ *Congress* ibi ko gbọdọ sọ o. Ọja Eyingbo ko mọ bi ẹnikan ko wa; a ki igbọ ki ẹnikan ninu nyin ma ṣe gulegule pe "Agbà la jẹ fun ẹnyin Dẹmọ" nitori irufẹ Agbà bẹ, Agbà-ilẹkun ni; Agba alailojuti ni, Agba alaini Fáyà ni; ko si ni Ajọ, Ajọ kò kun, ntan ara rẹ jẹ; ṣugbọn ọkanṣoṣo lo da ni loju eyini ni pe:—

Ina ti Ọlọrun tan ko si ẹniti o le pā. Igberaga ko le pā, Igberaṣanlẹ kò le pā, Arankan kò le pā, Iwa T'emi ṣā ko le pā, Inunibini kò le pā, Iṣọtẹ kò le pā,* bẹni iwa Adọ-nkia kò le pā.

Ẹnyin Agbà Ẹgbẹ *Congress* ilẹ yi, a sọ eyi fun itiju nyin.

Gbolohun kan ìgán t'awo ṣe!!!

---

## ÌJA KAN NBỌ, KOI TO JA!!

[ *Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU. ]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f' oji,

Ọrọ miran patapata ni a ti npete lati sọ ni ọsẹ yi ri; ṣugbọn, nitori àyan ọpọ enia, lati mọ ohun ti o da idi ẹjọ nla tiantian kan ti o wa ni Kōtu nisisiyi silẹ, li arin Lọya Adekunle Wright pẹlu Ọlọla Lọya Kitoyi Ajasa, O.B.E., ati Ọgbẹni J. Bagan Benjamin, C.E.; ngo pa ẹro akọkọ ti si apakan, ngo si jẹ ki ẹ ri awiye ẹjọ ti Lọya Wright kà.

Gẹgẹ bi ofin, a koi ti gbọdọ sọ ohunkohun si ẹjọ na, titi yiò fi pari; ṣugbọn, suru ti ō ni ọjọ ni.

## A Sensational Case.

IN THE SUPREME COURT OF NIGERIA.

Suit No. 354 of 1924.

*Between*

RUFUS ADEKUNLE WRIGHT,—*Plaintiff.*

*and*

KITOYI AJASA & JOSHUA BAGANDOJI BENJAMIN, —*Defendants.*

Plaintiff's statement of Claim filed on the 24th day of October, 1924, is as follows :—

1. By a Deed of Settlement dated on the 31st day of January, 1895, and made between Rufus Alexander Wright, Settlor of the one part, Emanuel Wright of the second part, Ṣodẹinde Alfred Leigh Sodipẹ and Defendant Kitoyi Ajasa as Trustees of the third part and registered as No. 91, Volume 26, at Page 356 of the Register of Deeds, Lagos. All those pieces or parcels of land situate at Ebute Metta, in the mainland of Lagos, commonly known as Wright's Farm in Wright's Town, Ebute Metta and farmlands situate at Agege described in the Deeds of Settlement as Isheri Lands, were assured unto the said Ṣodẹinde Alfred Leigh Ṣodipẹ and Kitoyi Ajasa as such trustees in fee simple subject to the following trusts, viz :—

(*a*) To the use of the said Emanuel Wright for life.

(*b*) And thereafter to the use of one William Joseph Ladipọ Wright when he attained the age of 30 years, and married, and to the heirs of his body lawfully begotten by him.

(*c*) And on failure of issue on the death of the said William Joseph Ladipọ Wright, in trust for the Settlor's other children who shall be living at the date of the death of the said William Joseph Ladipọ Wright.

2. Emanuel Wright died.

3. William Joseph Ladipọ Wright died at Abẹokuta, 1904, unmarried below the age of 30, and without any issue lawfully begotten by him.

4. The said Settlor Rufus A. Wright had other children lawfully begotten by him and living at the date of death of the said William Joseph Ladipọ Wright, viz :—

(*a*) Clarissa Layinka Agbebi (nee Wright,) born on the 15th of March, 1896, died on the 24th of April, 1924.

(*b*) Rufus Adekunle Wright, the Plaintiff, born on the 28th of August, 1900.

(*c*) Gladys Ayọdele Wright, born on the 11th of April, 1902.

5. S. A. Leigh-Ṣodipẹ died 1900.

6. The Defendant, Kitoyi Ajasa, as sole surviving trustee of Deed of Settlement has committed the following breaches of trust :—

(i) Permitting one Felicia Ayọdele Wright to dispose of several of the trust properties referred to in Para. 1, for her sole use and benefit.

(ii) Selling several portions of the trust properties for the benefit of the creditors of the said Felicia Ayọdele Wright.

(iii) Disposing of the sum of £1,691 received by him for the portion of the trust properties expropriated by the Government for the benefit of persons other than those entitled without investing same.

(iv) Converting to his own use and for the use of the creditors of the said Felicia Ayọdele Wright, the rents and profits received in respect of Agege farm-lands commonly called Isheri lands.

7. Felicia Ayọdele Wright died on the 17th of January, 1920, having by her last Will and testament appointed the Defendants her Executors and Trustees.

8. The said Will was exhibited for Probate which was granted by this Hon'ble Court on the 18th day of February, 1920, to above named Defendants.

9. The proceeds of the Sales made by Felicia Ayọdele Wright (deceased) had never been invested in accordance with the provisions of the said trust Deed by the Defendant, Kitoyi Ajasa.

10. The said Felicia Ayọdele Wright disposed of several portions of the said trust properties with the knowledge and consent of the Defendant Kitoyi Ajasa, and converted the money to her own use with his (the Defendant, Kitoyi Ajasa's) knowledge and consent.

The Plaintiff therefore claims :—

(*a*) As against both Defendants as Executors of the Estate of the said Felicia Ayọdele Wright on account of all the lands sold and covered by the said Deed of Settlement by the late Felicia Ayọdele Wright and for payment of one-third of the amount found due to the Plaintiff together with interest at the rate of 5 per cent per annum.

(*b*) As against the Defendant, Kitoyi Ajasa, as the sole surviving trustee on account of all the unauthorized sales of lands by the said Felicia Ayọdele Wright and all sales by him, as such sole surviving trustees.

(*c*) Replacement by the Executors of the Estate of the said Felicia Ayọdele

Wright of all monies which may be found due against her Estate in respect of the unauthorized sales of the said lands and for payment over to the Plaintiff of $\frac{1}{3}$ share of the total amount found due on the taking of the said account with interest at the rate of five per cent per annum.

(*d*) Replacement by the Defendant, Kitoyi Ajasa, of all proceeds of sale of the said trust properties sold by Felicia Ayọdele Wright or any other person in that behalf as from the 31st day of January, 1895, and proceeds of Sale made by him for the benefit of the creditors of the said Felicia Ayọdele Wright, and for payment of $\frac{1}{3}$ of the amount found due with interest thereon at the rate of five per cent per annum to the Plaintiff.

(*e*) Partition of the remaining lands unsold situate at Ebute Metta, known as Wright's Town, as between the three children refered to in Para. 4, living at the date of the death of William Joseph Ladipọ Wright.

(*f*) Partition of Agege Farm-lands described in the Deed of Settlement as Isheri Farm-lands as between the three children referred to in Para. 4, living at the date of the death of William Joseph Ladipọ Wright.

(*g*) An account of the Rents received by the Defendant, Kitoyi Ajasa, as trustee of the Deed of Settlement in respect of Isheri Lands, commonly known as Agege Farm-lands.

**Itumọ rẹ ni eyi :—**

Nipa iwe majẹmu ti a ṣe ni ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu Jẹnuari ọdun kọkandilọgbọn ọhun, larin Rufus Alexander Wright lapakan, Emanuel Wright lapakeji, Ṣodẹinde Alfred Leigh Ṣodipẹ ati Kitoyi Ajasa ti a pe lẹjọ ni olutọju ti apakẹta, ti a si fi ötẹ Ọba tẹ ni eto kọkanleladọrun, Iwe kẹrindilọgbọn, ojudinirinwo ewe o din mẹrin, ninu Iwe ilẹ ti Eko.

Gbogbo ilẹ to wa ni Ebute Metta ni afonifoji Eko ti a npe ni oko Wright eyiti a npe ni ilẹ Isheri ninu iwe majẹmu na ni a fi si abẹ itọju Ṣodẹinde Alfred Leigh Ṣodipẹ ati Kitoyi Ajasa lati tọju daradara fun awọn ẹniti a darukọ wọn si isalẹ iwe yi :—

(*a*) Fun lilo Emanuel Wright ni gbogbo ọjọ aiye rẹ.

(*b*) Ati pe lẹhin iku rẹ, ki gbogbo Ilẹ na bọ sọwọ William Joseph Ladipọ Wright nigbati o ba di ẹni ọgbọn ọdun, to ba gbe iyawo, ki ọmọ ti alarede rẹ ba bi fun u si jogun rẹ, lẹhin ti on papa ba pa ipo da kuro l'aye.

(*c*) Bi William Joseph Ladipọ Wright ko ba bi 'mọ titi o fi ku, ki a tọju gbogbo ilẹ na fun awọn ọmọ miran ti Rufus Alexander Wright ba tun bi, ti nwọn si wa laye ni ọjọ ti William Joseph Ladipọ Wright ba ku.

2. Emanuel Wright ku.

3. William Joseph Ladipọ Wright ku si Abẹokuta lai fi ọmọ s'aiye ni ogun ọdun ọhun, lai gbe 'yawo, nigbati koi ti to ẹni ọgbọn ọdun.

4. Rufus A. Wright to ni gbogbo ilẹ ti a nsọrọ rẹ yi, ni awọn ọmọ alarede miran to wa l'aiye l'ọjọ ti William Joseph Ladipọ Wright di ologbe :—(*a*) Clarissa Layinka Agbebi ti a bi ni ọjọ kẹdogun oṣu *March*, ọdun kejidilọgbọn ọhun, to si ku ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu *April*, ti ọdun ni.

(*b*) Rufus Adekunle Wright to pe ẹjọ nisisiyi, ti a si bi ni ọjọ kejidilọgbọn oṣu *August*, ọdun kẹrinlelogun ọhun.

(*c*) Gladys Ayọdele Wright ti a bi ni ọjọ kọkanla oṣu *April*, ọdun kejilelogun.

5. S. A. Leigh-Ṣodipẹ ku ni ọdun kẹrinlelogun.

6 O wa ku Kitoyi Ajasa nikan lẹnu rẹ gẹgẹ bi olutọju tabi *Trustee* ẹniti a fi ọkan tan, o si ṣe aidara nipa hihu iwa ẹniti ko yẹ ki a fi ọkan tan ti a o ka silẹ lẹsẹsẹ nisisiyi :—

Ekinni. :—O jẹ ki Felicia Ayọdele Wright ta pupọ ninu ilẹ ti a nsọrọ rẹ yi fun ire ara rẹ nikan.

Ekeji :—On Kitoyi Ajasa papa ta pupọ ninu ilẹ na lati san gbese ti Felicia Ayọdele Wright fi silẹ.

Ẹkẹta ;—Kitoyi Ajasa lọ ẹgbẹjọ o le pọnwun mọkanleladọrun owo ti o gba lọwọ Ijọba fun apakan ilẹ na ti Ijọba gba, fun awọn ẹniti ko tọ si rara, dipo eyiti iba fi pamọ si ibiti ele diẹ le gori rẹ fun awọn ti o tọ si.

4 Owo ti awọn to haya oko Agege ti a npe ... ile Iṣeri san, Kitoyi Ajasa lo o fun ara rẹ ati fun awọn ti Felicia Ayọdele Wright jẹ ni igbese.

7. Felicia Ayodele Wright ku ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu *January*, ọdun kẹrin ọhun, o si yan awọn mejeji ti a pe lẹjọ yi ni baba isinku ati ẹniti a fi ọkan tan ninu iwe Ipingun rẹ.

8. Kotu si yoda agbara fun awọn mejeji ti a pe lẹjọ yi lati ṣe iṣẹ ti a yan nwọn si gẹgẹ bi baba isinku ati ẹniti a fi ọkan tan, ni ọjọ kejidinlogun oṣu *February*, ọdun kẹrin ọhun.

9. Gbogbo owo ilẹ ti Felicia Ayọdele Wright ta, ko fi pamọ gẹgẹ bi ilana to wa ninu majẹmu ti a fi Kitoyi Ajasa ṣe olutọju rẹ.

10. Ko si eyiti o ṣẹhin Kitoyi Ajasa ninu gbogbo ilẹ ti Felicia Ayọdele Wright ta, ti o si lo owo rẹ fun ara rẹ pẹlu imọ ati ojẹgẹ Kitoyi Ajasa.

Nitorina nkan ti ẹniti o pe ẹjọ nbere ni iwọnyi :—

Işiro ati idamẹta gbogbo owo ilẹ ti Felicia Ayọdele Wright ta lọna to lodi si Iwe Majẹmu, pẹlu èlé şile kokan lori ponwun kọkan l'ọdun, lati ọjọ ti o ta nwọn.

(*b*) Ki Kitoyi Ajasa si şe akọ-nta tabi işiro gbogbo ilẹ ti on papa ta lọna ti o lodi si ofin Iwe Majẹmu.

(*c*) Ki awọn Baba isinku mejeji si pọ owo ilẹ ti o wa ninu Iwe Majẹmu yọ kuro ninu ogun Felicia Ayọdele Wright ki nwọn şe işiro gbogbo ki nwọn si fun ẹniti o pe nwọn lẹjọ ni idamẹta tirẹ nibẹ, pẹlu èlé şile kọkan lori ponwun kọkan l'ọdun lati ọjọ ti nwọn ti da owo ilẹ wọnyi pọ mọ ogun rẹ.

(*d*) Ki Lọya Ajasa san gbogbo owo ilẹ ti Felicia Ayọdele Wright ti nta tabi ti awọn ẹlomiran nta fun u, lati ọjọ kọkanlelogbọn oşu *January*, ọdun kọkandinlọgbọn ọhun, ki o si san gbogbo ilẹ ti on Kitoyi Ajasa papa ta nitori gbese Felicia Ayọdele Wright, ki o si fun on ti o pe e lẹjọ ni ida mẹta gbogbo owo wọnyi pẹlu èlé şile kọkan lori ponwun kọkan l'ọdun lati ọjọ ti awọn mejeji ti nta nwọn bọ.

(*e*) Ki Kitoyi Ajasa si yọda idamẹta ilẹ ti nwọn ba ta ku ni Ebute Mẹta fun on, gẹgẹ bi ipin ti o kan on larin ọmọ mẹta ti Rufus A. Wright bi ti a tọka si ni ẹsẹ kẹrin iwe yi, ti nwọn si wa lãye ni ọjọ ti William Joseph Ladipọ Wright ku.

(*f*) Ki Kitoyi Ajasa si pin ilẹ Agege ti a pe ni oko Isheri ni iwe Majẹmu fun awọn mẹtẹta ti a tọka si, to si wa laye ni ọjọ ti William Joseph Ladipọ Wright ku.

(*g*) Ki Ajasa şe akọnta tabi Işiro owo to ti gba lori ilẹ Isheri ti nwọn ti fi haya, ilẹ ti enia pupọ mọ gẹgẹ bi oko Agege.

Lọya Ọlayinka ati aburo rẹ Adeyẹmọ Alakija ni Lọya Rufus Adekunle Wright gba; Lọya Ajasa haya Lọya Eric O. Moore, J. Bagan Benjamin gba Ọlọla Lọya J. Egerton Shyngle.

Ẹ o tun ma gbọ bi ọrọ na ti nlọ si.

Emi ni tiyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

### FROM THE EDITOR'S OFFICE WINDOW.

**Advance. Pro-Cathedral.**

Giant Posters have been seen in town here and there giving chapter and verse regarding the series of events which will take place (31st October to 9th November) in connexion with the work of the Cathedral building; there are the renderings of choice musical pieces from great masters; none should miss this gala occasion.

**Is it the Lying Tongue?**

*On dit* that Mr. S. I. Samuel M.B.E. of Government House, will be created Assistant Resident, Colony; and Mr. George N. Martins of H. M. Customs, a Supervisor for Port-HarCourt. Any truth in this? Ask the policeman !!!

**"Boys," raise your hats to Good Old Garvey.**

It is with no little satisfaction we learn of the joyful news of the sympathetic hearing which our gallant friend Captain Garvey of the Colony Police accorded the Petition of the local Fire Brigade embodying certain grievances which, we are told require looking into.

We understand the men were kindly spoken to by the Captain regarding the subject-matter of their Memorial. Indeed,

"Kind hearts are more than coronets."

**Alas! what a Testimony!!!**

Bernice Alli (alias Joko) of Aliko Lane, Faji Market, for perjury was sentenced this week to 14 day's imprisonment, by His Honour Sir F. Vander Meulen in an action before the Court viz:—

FRANK MACAULAY
*Versus*
ABUDU KADIRI SERIKI.
SULE ABASI SERIKI.

Counsel for Plaintiff, O. Alakija of Alakija & Alakija
Counsel for Defendants, A. Latunde Johnson.

We understand this unfortunate woman tendered her evidence voluntarily in support of the Defendants' case.

---

## This, That, and The Other.

*By an Old Crow.*

### Retired Coaster's Rhyme.

Some witty and interesting stanzas, depicting life on the West Coast of Africa, appeared in the latest issue of the *Elder Dempster Magazine* under the caption "The Rhyme of An Old Coaster" and signed by J. H. Penington.

Two of them run as follows:—

"Behind time! Well, let's push on to Lagos!
Where each white man's the son of a Duke,
With his college badge stuck on his blazer,
He'll prove it by bell and by book;
And if you don't boast an ancestry,
And *you* ain't got that sauve English drawl;
If *you* don't play cricket, well, cancel your ticket,
You're no good in Lagos at all.

The next port you'll touch is Forcados,
Bound for Warri and Sapele creeks;
And you'll learn all about a *mosquito*
When you've been there a couple of weeks,
And there's some that will tell you that fever,
Can be cured with a bottle of gin;
Well, try it, *and pass on to Heaven*,
By way of the *Bight O' Benin*."

### Election Rowdyism.

"During an election meeting at Clay Cross, a man called Col. Kelly, V.C., the Conservative candidate, a liar. The man was requested to withdraw his remark but refused. He repeated it, whereupon Col. Kelly *thrashed* him amid the applause of the audience..."

The above was extracted from the *Reuter's Telegrams* for 25. 10. '24.

In modern times, Oratory is not only *the thing* in electioneering campaign—Physical Exercise: *Boxing* and *Wrestling* are perhaps sometimes necessary in political arguments.

AN OLD CROW

## LABARI LATI ABẸOKUTA.

Ni ọsẹ to kọja, a gbọ pe Alake ati awọn Igbimọ gbe agogo sode pe ki olukuluku enia mura lati san owo ori wọn (*Tax*) ati pe ẹniti ko ba san tirẹ titi ijọ mẹta (eyini ni titi ọsẹ yi yio fi jalẹ) o mbẹ ninu ewu ẹjọ.

A gbọ pe awọn akọwe ti o ngba owo yi ni ati pin si ọna mẹrin, Ẹgba Alake, Ẹgba Oke-Ọna, Ẹgba Agura ati Ẹgba Olowu, ni Kotu (*Court*) ni a si ngba owo yi, Mr. N. Adetayọ ni akọwe ti Ẹgba Alake, a si gbọ pe Ọgbẹni Titcombe Aṣoju Alake (*Private Secretary*) ni a ran lati ran Mr. Adetayọ lọwọ nigbati iṣẹ pọ rekọja fun u.

Ọlọla D. Ṣowẹmimọ ati awọn Igbimọ ni a gbọ pe nwọn nṣe alabojuto owo yi, gbogbo awọn Ẹgba si nfi t'ayọ-t'ayọ da owo na. Ọgbẹni S. O. Akinbọla ni akọwe ti a gbọ pe a yan fun ati gba owo ti Ẹgba Oke-Ọna.

Ohun kan ni awa gbọ ti o ya ni lẹnu ni pe ọmọ ti o nkọṣẹ ni lati san ninu owo yi. Ṣugbọn a sọ fun ẹniti o sọ fun wa pe ko le ri bẹ ẹ, nitoripe ko ti ri bẹ lati ẹhin wa, ẹniti o nkọ iṣẹ yala Gbẹnagbẹna ni o, tabi Alagbẹdẹ Irin, tabi Ọmọle iṣẹ to wu ko le jẹ, ti a ba ti pe o nkọṣẹ na ni Ọlọrun nikan lo mọ bawo ni o ṣe njẹun, boya ẹlomiran ọga rẹ ko fun ni ṣile kan ni oṣu mẹfa, ibo lo ti ma ri owo yi da, nitorina. a ni ireti pe awọn Ọba wa ati awọn Igbimọ wa ko ni fi dandan le pe ki awọn ọmọṣẹ ma san owo yi titi di igbati ọga wọn yio fi sọ wọn di ominira. Kabiyesi o, ilu wa na yio toro dandan lọtẹ nyin o. *Amin.*

Ninu Iwe-irohin ti *Spectator* ti o jade ni ọjọ kejidilogun oṣu yi (*October*) a ri ka ninu rẹ pe, ninu Ajọ Igbimọ nla ti *Nigeria* ti a ṣe ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi na, ibere ti aṣoju Ẹgba ni Igbimọ nla yi bere lọwọ ọga agba ti Ọkọ-ilẹ nipa ọkọ ti ima pẹ ki o to gunlẹ ni Lafẹnwa.

A le fi han awọn ti o nka Iwe-irohin rẹ pe otitọ ni eyi, loni ti mo nkọwe yi Ọkọ na tete de pupọ ju, o de Lafẹnwa ni nkan agogo mẹjọ kọja diẹ, nigbamiran o ma ngunlẹ ni agogo mọkanla, yio jẹ didun inu gbogbo ara Abẹokuta ti Ọkọ yi ba nle gun si Lafẹnwa ni nkan agogo mẹfa gan tabi mẹfa abọ, ṣugbọn ti oni agogo mẹwa mọkanla yi ko wọ rara.

KEKERE ẸGBA.

## STOP PRESS!

Mr. Frank Morrick Baddeley, B.A. (Cantab) of the Inner Temple, Barrister-at-law, Under Secretary, Straits Settlements, was appointed Chief Secretary to The Government, (Nigeria) *vice* Sir Donald Cameron, lately appointed Governor of Tangayika, East Africa—*Eko Akete* Wireless.

### "EKO AKETE" D'ARABA T'APA ỌMỌDE KỌ KA, A YIN OLUWA!

Lati oni lọ, "*Eko Akete*" yio di torọ torọ (3d) ni tita fun ọkọkan, a o si ma tẹ to ẹgbẹgbẹjọ lọsọsẹ (*1,600 copies weekly*).

### IPADE TUNLUṢE.

Ipade Tunluṣe yio wa ni ọsan yi ni agogo mẹrin.




*Reduced 3/- each.*

ACCESSORY AND PARTS

**For Bicycles, For Motors, For Gramophones.**

*ASK FROM*

KADUNA STORES.

79, and 81, Ọdunfa Street, Lagos

*Near the palatial building of the late Mr. A. W. Thomas.*

And also expert in repairing all.

S. ADE CLAY.

## JAMES AKINDELE SULE,

*Ti a bi ni ọdun 1870, ti o si ku ni ọjọ 18 October, 1924.*

Iya rẹ, Emma Taiwo, jẹ ara Abẹokuta, ibatan rẹ pataki ti a si mọ mo ọ ni Ọgbẹni David Dawọ, baba iya M. S. Taiwo Ologbe, ati iya awon Ọgbẹni Akin ati Adeniyi Olugbile ti Ebute Mẹta.

Ibi a nṣowo lati ilu kan de ekeji ni Emma Taiwo fi ni ọkọ l'Ogbomọṣọ, ti o si bi Ọgbẹni James Sule ati ẹgbọn rẹ obinrin ti o wa ni ile rẹ nisisiyi.

Ni 1867 ti awọn Ẹgba ko ile Oyinbo Oniwasu l'Abẹokuta, Daddy David Dawọ pẹlu awọn Onigbagbọ ti o binu wa si Ebute Mẹta, o si jẹ ọkan ninu awon agbalagba mejila ti Ijọ *St. Jude's* Ebute Mẹta. Nigbati Mammy Emma Taiwo ri pe ẹgbọn on ba awọn Oyinbo Oniwasu wa si Eko ko si pada, on papa wa si Ebute Mẹta, ti on ti ọmọ rẹ Ologbe yi.

Daddy David Dawọ ba aburo rẹ damọran pe ọmọ ti a ko ba fi si ọdọ enia ko le gbọn, bẹni o fi James Sule sọdọ *Bishop* Crowther, o si nlọ si *School Bread rut*

Nigbati o fi ọdọ *Bishop* Crowther silẹ, o lọ gbe ọdọ Ọgbẹni D. E. Williams ( Aganga ), lẹhinna o lọ kọ iṣẹ gbẹnagbẹna lọdọ Ọgbẹni A. E. Coates ni Feb. 1886.

Nigbati o kọ iṣẹ tan, o bẹrẹ si iṣe iṣẹ gbẹnagbẹna lọdọ Ọgbẹni I. A. Cole ( Mr. Ogunmọdẹde ), o tun ṣe iṣẹ diẹ ni P.W.D. lẹhin na o wa kọ ibiti o ku si yi ni pẹtẹsi kekere, ti o fi ọpa gba, nibẹ li o sin oku iya rẹ Emma Taiwo.

Ki iya na to ku, nigbati o ri iru itọju ti ọmọ rẹ yi fun on o gba adura fun u bayi pe, bi o ba pe ẹnikan ki Ọlọrun jẹki ẹni mẹrin ma da a lohun, itumọ eyi ni pe ki Ọlọrun bu si iṣẹ ọwọ rẹ.

Ologbe James Sule mọ iṣẹ gbẹnagbẹna rẹ dajudaju, ṣugbọn on ti ko jẹki o ma gba iṣẹ lode tabi iṣẹ a nkọ ile kiri ni pe awọn oṣiṣẹ ti o ba fi si ẹnu iṣẹ ki ifi igbagbogbo tẹ ẹ lọrun, bẹni on ko le joko ti wọn nigbati o jẹ pe iṣẹ tun wa fun on nibomiran, ẹniti o fun on ni iṣẹ ṣe yio bẹrẹsi iṣọ, bẹni ara on ko gba iwọsi nitori eyi lo ṣe bẹrẹ si iṣe iṣẹ ni ile, ti o nkan apoti, ipeku ati nkan miran titi lọ fi de posi, Ọlọrun si ba a ṣe e, opopo ibiti o wa ( *Custom Street* ) jẹ ibiti ero nwọ.

Ni ọdun pupọ sẹhin li o kọ ile ibiti o nta ọja ni pẹtẹsi mẹta, ki o to ku ni alẹ *Saturday* ọjọ 18 oṣu to kọja

O fi ọmọ ọkọnrin meje ati obinrin marun silẹ, eyi akọbi ọkọnrin nṣiṣẹ lọdọ awọn *Lawyer* Alakija nisisiyi,

O fi ẹgbọn rẹ obinrin silẹ pẹlu ọmọ iya rẹ, ẹniti ko ro pe on le fi si aiye lọ.

AIYETORO.

---

### AKANSE ORIN FUN IJUBA ẸGBẸ TUNLUṢE

( *DEMOCRATIC PARTY.* )

[ Lati ọwọ AKIRIMANU.]

Olowo ko ma si nkan—
Awon to d'aja s lẹ nwọn nfẹ tun ṣe,
T'olori t'elese nwọn tun pada ka nwọgbọn
Lati tun p'Ọba wa l'Ọba.
Iwọ eke Oloye k'o lọ wa bi gbe
Tẹn m'Ọba nyin sọkò, tẹ tun pada ka nsure
Ṣ'Oba Oluwa lo tobi (oro aye)
E lọ bẹbẹ ka lọ gba'we are
Aiye ti yi, ṣa ẹ jẹ pada lọ k'ọgbọn.

AKIRIMANU.

---

Ọgbẹni T. A. Ẹrinoṣọ jẹ Ojulowo Oniṣowo. O nfi ọja ranṣẹ, o nta ọja, o si nra ọja, o jẹ Oniṣowo pataki ninu Ekurọ, Epo, ati orișiriṣi ọja miran. Ọgbẹni na si tun jẹ ẹniti o gba iwe ati ma ta Ilẹ, Ile tab Oko.

Ẹ lọ fi Ọja nyin fun u ni :—

19, Opopo Tinubu,

Tabi ki ẹ kọwe si ni :—P.O. Box 242,

EKO.



**Kruschen Salts.**

**2/9 a Bottle containing 96 doses.**

### HE SINGS IN HIS BATH.

Hard things have been said about the man who sings in his bath, disturbing other people's sleep, but please understand his feelings he is singing out of the pure joy of his heart. He gets up feeling brimful of health and energy, he's glad to be alive, he welcomes the advent of another day of glorious existence, he offers up a song of praise—even though it's only a music hall song—having been born in such a wonderful world.

Well, that's something to make a song about, isn't it—you who grumble at his musical efforts—you would make music too if you got up feeling as he feels.

And you will feel that way—just bursting with the need of expressing sheer joy of living—if you take your dose of Kruschen Salt.

The little dose that does so much.

Just sufficient to cover a 6d. piece, tasteless in your breakfast cup of Tea or Coffee.

It will keep your kidneys and liver in order, it will remove all waste matter clogging the system, purifying and refreshing the blood, make you tingle in every fibre with new health, new vigour, new joy.

*Obtainable from all Stores and Chemists. Sole importing Agents for Nigeria*: B. ANDERSSON & CO. LTD., *P.O. Box 145, Lagos.*

---

**prings! Springs!! Gramophone Springs!!!**

ALSO

**Isolated Bottles; Vaccum Flasks.**

Messrs Remi Macarthy & Son, of 5, Taiwo Street, Lagos, has just received a consignment of Springs adapted either for English or German Gramophone. Also (Thermos Bottle) Vaccum Flasks to keep water hot for 24 hours. The Springs and Flasks are sold at very moderate prices. Come and pick yours ere the Stock exhausted. The Flasks are assorted sizes and bodies.

AWỌN OKUN-ERỌ TI GRAMOPHONE FI NKỌRIN, ATI IGO IFI OMI GBIGBONA SI

( T'omi ko ni fi tutu gba wakati mẹrinlelogun ).

Awọn Rẹmi Macarthy *and Sons* ti nwọn ngbe 5, Taiwo *Street*, l'Eko ni awọn Okun-Ẹrọ ti *Gramophone* fi nkọrin lọwọ fun tita. Nwọn ṣẹṣẹ ri wọn gba lati Ilu Oyinbo, ema le lo wọn fun Ẹrọ *Gramophone* yala ti Gẹsi tabi ti Jamani. Wọn tun ni Igo ti a le fi omi gbigbona si gba wakati mẹrinlelogun. Owo pọ ọ ni wọn nta nkan wọnyi ( Igo omi gbigbona fun tita wa ) sure tete ki o wa ra tirẹ ki ẹran rẹ ma ba bi obukọ.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun ẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn oniṣowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKE Oniṣowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikanọkọ, Iṣo lorisirisi, Kọkọrọ (Iṣika) t'ilẹkun ati t'apoti lorisirisi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorisirisi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọsan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorisirisi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

On si ni aṣoju awọn ẹgbẹ Oyinbo oniṣowo to njẹ Arnold Whitehead Ltd. to wa n Manchester (Ni'lu Oyinbo) to si nranṣẹ oriṣi-riṣi ọja fun-ni lat'ọdọ wọn ni Eko ati agbegbe rẹ. Lọ ṣ'abere ẹhin ọrọ nipa owo yi lọwọ rẹ ni Ṣabu rẹ tabi ki o kọwe ranṣẹ si ki o fi ṣọwọ sinu apoti ikọwe si t'Ọba P.O. Box No. 796, Eko, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at A. Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

**GOOD MARKET.**

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

**Cable Address:—**
"Steinafrik" HAMBURG

**E. H. STEIN & Co.**
HAMBURG, Neuwall 16/18.
Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

---

**Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!**

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from :—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

**Highly Recommended:**

THE

# Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**32s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

## JACOB AJAYI,

*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

ILU ẸPẸ KO KERE L'AWO ẸIYẸ O BA LO GE.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ti No. 88 Opopo nla l'Eko nibi ṣeṣẹ ṣi Ile Egbogi to kẹriri kan si eti Ebute l'Ẹpẹ.

Ile Egbogi na ko jina si Ile-Ọja awọn Oyinbo Oniṣowo John Holt.

Ọgbẹni yi ni Ajalolẹru Egbogi ni Ṣabu na, eyiti ki foju arunkarun ba'lẹ gẹrẹ ti a ba ti lo wọn.

Ẹ wa dan a wo: bẹ lẹ o ba.

Ọpọku-ọyọku ni owo tita wọn.

## T. A. Erinosho,

*Forwarding, Shipping, Buying, Selling and Commission Agent, Land and Estate Agent, Produce Merchant, Licensed Auctioneer & Valuer.*

19, Tinubu Street, P.O. Box, 242, Lagos, Nigeria.

### Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi oriṣiriṣi Egbogi lo ṣẹṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo oriṣiriṣi, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbamẹji, ogun Aran oriṣiriṣi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mă to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.